# ISỌDIMIMỌ́ ISAIAH

### Isaiah 6:1-13

### ẸKỌ 350 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitorina Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jiya lẹhin bode" (Heberu 13:12).**

**Iṣẹ́ Isaiah**

Ọlọrun ni iṣẹ pupọ fun Isaiah lati ṣe. Ọlọrun pè e lati kilọ fun awọn Ọmọ Israẹli nipa idajọ ti yoo wá sori wọn nitori ẹ̀ṣẹ wọn; ati lati sọ fun wọn nipa Jesu, Messia ti O n bọ̀ wá gba iyoku ile Israẹli là. Ki i ṣe pe Isaiah yoo sọ fun wọn nipa wiwa Jesu ni akọkọ nikan, gẹgẹ bi o ti ṣe nigba ti o kọ akọsilẹ wi pe: "Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika rẹ̀: a o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Ayeraye, Ọmọ-Alade Alafia"; ṣugbọn Isaiah tun sọ nipa akoko naa ti Jesu yoo jọba ni ayé yii nigba Ijọba Ẹgbẹ̀rún Ọdún. "Aginju ati ilẹ gbigbẹ yio yọ̀ fun wọn: ijù yio yọ̀, yio si tanna bi lili" (Isaiah 35:1). "Ṣugbọn ki ẹnyin ki o yọ̀, ki inu nyin ki o si dùn titi lai ninu eyiti emi o da: nitori kiyesi i, emi o da Jerusalemu ni inudidùn, ati awọn enia rẹ̀ ni ayọ̀ … a ki yio si tun gbọ́ ohùn ẹkún mọ ninu rẹ̀, tabi ohùn igbe" (Isaiah 65:18, 19).

**Imurasilẹ fun Iṣẹ Naa**

Ki Isaiah to le sọ asọtẹlẹ nla wọnyii fun awọn eniyan naa, ọkàn oun tikara rẹ̀ ni lati wà ni imurasilẹ. Lai si aniani a ti gba ọkàn Isaiah là ki o to bẹrẹ si sọtẹlẹ. Ninu ipò idalare yii, o ti sọ ọ̀pọlọpọ asọtẹlẹ ti o wú ni lori, o si ti waasu fun awọn Ọmọ Israẹli. Ṣugbọn ki o ba le ṣe iṣẹ nla ti o wà niwaju rẹ̀ lati ṣe yii, o gbà pe ki Isaiah ni ìrírí ti o jinlẹ ju bayii lọ -- eyi nì ni isọdimimọ́.

Isaiah ti bẹrẹ iṣẹ asọtẹlẹ rẹ̀ lati igba ijọba Ussiah ọba. Ọba yii jẹ olooototọ fun ọ̀pọlọpọ ọdún; ṣugbọn ni opin ijọba rẹ o ṣaigbọran si Ọlọrun, o si di adẹtẹ. A ti kọ́ ẹ̀kọ́ pe bi ọba kan ba dẹṣẹ, ọ̀pọlọpọ ninu awọn ti o wà labẹ ijọba rẹ ni yoo tẹle apẹẹrẹ buburu rẹ̀. Nitori naa a mọ pe ni akoko ti Ussiah kú, iwa-ayé awọn Ọmọ Israẹli kò dán mọran mọ́.

**Adura fun Israẹli**

Isaiah lọ si Tẹmpili lọ gbadura. Dajudaju ọ̀ràn awọn Ọmọ Israẹli wọnyii n fẹ adura gidigidi. Ọlọrun, jọwọ fun Israẹli ni ẹmi ironupiwada! Oluwa, ṣaanu fun wọn!

Bi o ti n gbadura, ogo Ọlọrun sọkalẹ sori rẹ̀, o si ri ninu iran bi Oluwa ti joko lori itẹ́ ti o ga, ti o si gbé ara Rẹ̀ soke, iṣẹ́tí aṣọ Rẹ̀ si kún Tẹmpili.

Nigba ti a ba ni iwuwo lọkàn lati gbadura fun awọn ẹlomiran, tabi fun iṣẹ Oluwa, Ọlọrun a maa fà wá mọra, awa yoo si ri diẹ ninu ogo Rẹ̀. Awa a maa ni idapọ mimọ́ pẹlu Rẹ̀ bi a ti n ṣiṣẹ fun Un.

Wo irú anfaani ti Isaiah i ba sọnu bi oun ba ti wi pe eniyan buburu saa ni awọn Ọmọ Israẹli, kò si ṣanfaani lati maa gbadura fun wọn. Bi igbala kò ba jamọ nnkan ni oju wọn, eredi wahala ti rẹ̀. Bi o ba ni irú èro bayii lọkàn rẹ̀, oun ki bá ti lọ si Tẹmpili lati gbadura, bẹẹ ni oun ki bá ti ri ogo Ọlọrun.

Bi o ti wù ki awọn eniyan jẹ́ ọlọkàn lile tó, iṣẹ́ ti Onigbagbọ́ ni lati gbadura tọkantọkàn si Ọlọrun fun igbala wọn, ati lati ni agbára Ọlọrun ninu igbesi-ayé rẹ̀ to bẹẹ ti ẹlẹṣẹ yoo fi ri i bẹẹ. Awọn eniyan ti fi adura fa isọji sọkalẹ nigba miiran nibi ti awọn eniyan ti fẹrẹ sọ ireti nù pé ẹnikẹni le ri igbala.

**"Jẹ alagbara!**

**Maṣe wi pe, 'Buburu ni awọn ọjọ.**

**Ẹjọ ta ni?'**

**Ki o si kawọ gbera ki o dagunlá**

**---Kinla!**

**Dide, sọrọ pẹlu igboya, ni orukọ Ọlọrun."**

**Ogo Ọlọrun**

Ki i ṣe kiki pe Isaiah ri iran Oluwa nikan ṣoṣo, ṣugbọn o ri awọn serafu duro lori itẹ Ọlọrun. Wọn jẹ́ irú ẹda ti Isaiah kò ti ri ri. Ẹni kọọkan wọn ni iyẹ mẹfa. Wọn fi iyẹ meji bo oju wọn. Wọn mọ ohun ti ẹwà iwa mimọ́ Ọlọrun jasi, wọn si le ṣe alai ka ara wọn yẹ lati wo oju Rẹ̀.

Nigba ti a ba bẹrẹ si woye iwa mimọ́ Oluwa, a o ri pe awa ko yẹ ni ẹni ti a ba maa pe ni ọ̀rẹ́ tabi arakunrin Rẹ̀ (Heberu 2:11). "Kili enia, ti iwọ fi nṣe iranti rẹ̀? ati ọmọ enia, ti iwọ fi nbẹ̀ ẹ wò?" (Orin Dafidi 8:4). Nigba ti a ba wà ni ile Ọlọrun a kò gbọdọ huwa lọná ti yoo tabuku si ogo Rẹ̀. Awọn serafu yii fi meji ninu iyẹ wọn bo ẹsẹ, wọn si n fi iyẹ meji iyoku fò lati mu aṣẹ Ọlọrun ṣẹ kánkán.

Bi awọn serafu wọnyii ti n fò yi itẹ Ọlọrun ka, ekinni si ke si ekeji pe, "Mimọ́, mimọ́, mimọ́, li Oluwa awọn ọmọ-ogun, gbogbo aiyé kún fun ogo rẹ̀." Bi awọn eniyan ba le maa yin Ọlọrun logo, wọn o mọ riri ogo ti o wa nibi gbogbo. Oju Rẹ̀ wà ni gbogbo ayé, ibikibi ti awọn eniyan ba si gbé n gbadura, Oun yoo wá sibẹ lati dahun. Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan maa yin Oun. Gbogbo awọn ẹ̀da Ọrun ni wọn n yin Ọlọrun logo.

Bi awọn serafu ti n kọrin, ogo Ọlọrun kún inu Tẹmpili gẹgẹ bi eefin. Awọn opó Tẹmpili paapaa mì nipa agbára ti o wà ninu rẹ̀. Njẹ iwọ ha le woye irú ipò ti Isaiah wà nigba ti o ri gbogbo ogo ati agbára yii? Dajudaju yoo mọ ara rẹ̀ ni alai yẹ. Bẹẹ ni orilẹ-ède Israẹli kún fun ẹ̀ṣẹ pupọ lakoko yii! Ki ni ṣe ti Ọlọrun ni lati fi ara Rẹ̀ hàn fun wọn ninu iru ogo nla bayii? Isaiah mọ̀ wi pe oun ni lati ni iwà-mimọ́ sii ninu ọkàn rẹ̀. O fi irẹ̀lẹ̀ ke pe Ọlọrun lati ran oun lọwọ.

Nigba ti a ba mọ aini wa ti a si n fẹ iranlọwọ lati ọdọ Ọlọrun, nigba naa Oun yoo ràn wá lọwọ. Nigba ti a ba fi irẹ̀lẹ̀ tọ̀ Ọ wá, Oun yoo gbọ́ ohùn ẹ̀bẹ̀ wa yoo si dahùn.

**Ọkan Funfun**

Bi Isaiah ti n gbadura, ọ̀kan ninu awọn serafu mú ẹ̀ṣẹ́-iná ni ọwọ́ rẹ̀ lati ori pẹpẹ wá, o si fò wá sọdọ Isaiah, o si fi kan an ni ẹnu, o si wi pe, "Kiyesi i, eyi ti kàn etè rẹ, a mu aiṣedede rẹ kuro, a si fọ ẹ̀ṣẹ rẹ nù."

Nigba ti a gba ọkàn Isaiah là, a ti dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i, ani awọn ohun aitọ ti o ti ṣe. Ṣugbọn ẹda ẹ̀ṣẹ, ti a maa n mẹnu kan ninu Bibeli bi ẹyọ ohun kan ṣoṣo (ẹ̀ṣẹ), wà nibẹ sibẹ. O yẹ ki a sọ ọ di mimọ́. Isọdimimọ́ ni o n fọ ọkàn, ti o si n wẹ ẹ mọ́.

Nigba ti Dafidi dẹṣẹ, o gbadura pe ki a nù irekọja oun nù kuro. Ohun ti o n sọ nihin ni pe, "Dari awọn ẹ̀ṣẹ ti mo ti ṣẹ̀ ji mi." Lẹyin eleyii ni o tun wi pe: "Wẹ̀ mi li awẹmọ́ kuro ninu aiṣedede mi, ki o si wẹ̀ mi nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ mi" (Orin Dafidi 51:1, 2). Eleyii ni n sọ nipa isọdimimọ́, ọkàn funfun.

Isaiah ti gbọ́ bi awọn serafu ti n kọrin nipa ẹwa iwa-mimọ́ Ọlọrun. Bi oun bá fẹ́ lati sin Ọlọrun ni ọ̀na itẹ́wọ́gbà, oun ni lati jẹ́ mimọ́ pẹlu. Orukọ miiran ti a n pe isọdimimọ́ ni iwa-mimọ́.

Ọlọrun wi pe, "Ẹ jẹ mimọ́; nitoriti emi jẹ mimọ́" (1 Peteru 1:16). Ọlọrun n fẹ́ ki a jẹ́ mimọ́ **ni aye yii**. O bura fun Abrahamu, "Pe on o fifun wa, lati gbà wa lọwọ awọn ọtá wa, ki awa ki o le ma sin i laifòya, ni mimọ́ iwa, ati li ododo niwaju rẹ̀, **li ọjọ aiyé wa gbogbo**" (Luku 1:73-75). Ikú kò le sọ eniyan di mimọ́.

**Mẹtalọkan Pesẹ**

Ẹ jẹ ki a ṣe akiyesi pe Mẹtalọkan Mimọ́ fi ara hàn ninu iran yii. Awọn serafu n kọrin wi pe, "Mimọ́, mimọ́, mimọ́," wọn n yin Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ́. Nigba ti Oluwa sọrọ̀, O wi pe, "Tali **emi** o rán?" O si tun beere wi pe, "Tani yio si lọ fun **wa**?" Ẹni ti o wa nibẹ ju Ẹni kan lọ.

Awọn miiran le wi pe, Jesu kò si ni ibi kan titi di igba ti a fi bi **I** ni Bẹtlẹhẹmu. Ṣugbọn nigba ti Johannu Apọsteli n sọ nipa iriri Isaiah ninu Tẹmpili, o wi pe, Jesu wà nibẹ. Johannu sọ nipa iṣẹ-iyanu ti Jesu n ṣe nigba ti O wà ni ayé, o si wi pe awọn eniyan naa kò gbà A gbọ́ gẹgẹ bi wọn kò ti gba Isaiah gbọ́ ni ọ̀pọlọpọ ọdún ṣaaju akoko yii. Isaiah wi pe: "O ti fọ́ wọn loju, o si ti se àiya wọn le; ki nwọn má ba fi oju wọn ri, ki nwọn má ba fi ọkàn wọn mọ̀, ki nwọn má ba yipada, ki emi má ba mu wọn larada" (Johannu 12:40). Johannu wi pe, "Nkan wọnyi ni Isaiah wi, nitori o ti ri ogo rẹ̀, o si sọ̀rọ rẹ̀ (Jesu)"

(Johannu 12:41). Eyi yii fi hàn pe Ẹmi Mimọ́ ti fi hàn fun Johannu pe Jesu wà ninu Tẹmpili nigba ti a sọ Isaiah di mimọ́, ni ọ̀pọlọpọ ọdún sẹyin ki a tó bi Jesu ni Bẹtlẹhẹmu.

**Jijẹ Ipe**

Iriri ologo ni o jẹ́ fun Isaiah lati ri ojurere Ọlọrun lọnà pataki bayii; ṣugbọn ogo ati ibukun ti o ri gba yii ki i ṣe fun oun nikan ṣoṣo. A fun un ni iranwọ yii lati fun un ni agbára ati ọgbọ́n lati sọ fun Israẹli apẹyinda nipa ti Oluwa. Gẹrẹ ti ibukun yii tẹ ẹ lọwọ, ni o gbọ́ ohun Oluwa wi pe, "Tali emi o rán, ati tani o si lọ fun wa?" O dahun lọgan wi pe, "Emi nĩ, rán mi." O mọ ara rẹ̀ ni alaiyẹ sibẹ, ṣugbọn bi iṣẹ ba wà lati ṣe, o ṣetan lati ṣe e.

Ki i ṣe ohun ti o rọrùn. Awọn eniyan wọnyii ki yoo feti si Isaiah. Ọpọlọpọ igba ni yoo rò wi pe iwaasu rẹ̀ kò ja mọ́ nnkankan. Ṣugbọn Ọlọrun sọ fun un pe ki o lọ, o si gbọran. Nitori pe awọn eniyan naa fẹran ẹ̀ṣẹ, wọn ki yoo le ri ẹwà ti o wà ninu Ihinrere. Wọn ki yoo gbọ́ ihin ayọ̀ igbala. Wọn yoo sé aya wọn le to bẹẹ ti Ẹmi Ọlọrun ki yoo le wọle. Ṣugbọn sibẹ Isaiah ni lati waasu.

**Yoo ti Pẹ To?**

Isaiah mọ̀ pe iṣẹ na wuwo, o si beere pe, "Yio ti pẹ to?" Yoo ti pẹ to ti Israẹli yoo maa jiya nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀? Yoo ti pẹ to ti wọn yoo maa kọ iṣẹ ti Ọlọrun rán si wọn? Awọn Ju ti jiya fun ọ̀pọlọpọ ọdún lati igbà ni, wọn si n beere sibẹ wi pe, "Yio ti pẹ to?" Yoo ti pẹ to ki wọn to mọ Messia wọn ti yoo si mu idasilẹ wá fun wọn?

A tú awọn Ju ká kuro ni ilẹ Palẹstini lẹyin ti wọn kan Jesu mọ́ agbelebu. Ojo dẹkun lati maa rọ̀ sori ilẹ wọn, nitori naa ounjẹ ṣọ̀wọ́n. Ile wọn di ibajẹ gẹgẹ bi Isaiah ti sọ tẹlẹ.

"Ṣugbọn sibẹ, idamẹwa yio wà ninu rẹ̀, yio si pada." Isaiah wi pe awọn diẹ yoo pada. Jesu wi pe, "Jerusalemu yio si di itẹmọlẹ ni ẹsẹ awọn Keferi, titi akoko awọn Keferi yio fi kún" (Luku 21:24).

Akoko awọn Keferi fẹrẹ dopin. Ojo ti bẹ̀rẹ̀ si irọ̀ ni Palẹstini, bẹẹ ni awọn Ju ti bẹ̀rẹ̀ si pada lati orilẹ-ède gbogbo lati maa gbé Ilẹ Mimọ́ nì. Ọrọ Ọlọrun ti bẹ̀rẹ̀ si ṣẹ.

## AWỌN IBEERE

1 Sọ diẹ ninu awọn ohun rere ti Isaiah sọ asọtẹlẹ rẹ̀.

2 Iru imurasilẹ ọkàn wo ni Isaiah ni lati ṣe fun iṣẹ nla ti o wà niwaju rẹ̀?

3 Nibo ni Isaiah wà nigba ti o ri iran yii?

4 Ki ni Isaiah ri?

5 Bawo ni ọkàn Isaiah ti ri nigba ti o ri gbogbo ogo yii?

6 Ki ni serafu naa ṣe si Isaiah? Ki ni o si wi?

7 Ki ni ọ̀rọ miiran ti a n lò fun isọdimimọ́?

8 Bawo ni a ṣe mọ pe a le jẹ́ mimọ́ ni ayé isisiyii?

9 Bawo ni a ṣe mọ pe Jesu wà ninu Tẹmpili lakoko yii ki a to bi I ni Bẹtlẹhẹmu?